fi ìwà ìrẹ̀lẹ̀ jẹ́wọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ. Múra láti sọ bí àwọn ẹ̀ṣẹ̀ náà ti rí ní pàtó. Dárúkọ wọn lọ́kọ̀ọ̀kan bí o ṣe ń gbàdúrà. Kò sí ohun tí ó pamọ́ lójú Ọlọ́run (Hébérù 4:13).

*Ọlọ́run Bàbá: Mo jẹ́wọ́ pé mo yapa kúrò lọ́dọ̀ Yín, mo sì padà sí ọ̀nà ìgbésí aiyé mi àtijọ́. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí (**Bẹ̀rẹ̀ sí í sọ àwọn ohun tí o ṣe, láti gbà pé ẹ̀ṣẹ̀ ni wọ́n**). Mo fẹ́ padà sọ́dọ̀ Yín. Mo fi aiyé mi fún Yín lẹ́ẹ̀kan sí i; mo sì ṣèlérí láti dúró lórí ìpinnu mi. Mo dúpẹ́ Bàbá, fún àánú àti ìfẹ́ Yín; àti fún Jésù Krístì tí Ẹ rán láti kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi. Ní Orúkọ Ńlá Jésù ni mo gbàdúrà yìí. Àmín.*

## Kí ló kàn?

Padà sí ṣọ́ọ̀ṣì rẹ, tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì òmíràn tí ó wù ọ́, kí o sì gbèrò láti máa lọ nígbà gbogbo. Yóò jẹ́ ìrànlọ́wọ́ fún ọ tí o bá dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ àdúrà kan. Rántí láti ka Bíbélì rẹ lójoojúmọ́. Sa gbogbo ipá rẹ láti máa gbé ìgbésí aiyé ìwà-mímọ́. Yẹra fún àwọn ènìyàn, àwọn nǹkan, àti gbogbo ibi tí ó lè fà ọ́ padà sínú ẹ̀ṣẹ̀. Kàkà bẹ́ẹ̀, wá àwọn ọmọlẹ́yìn Krístì òtítọ́ láti bá ṣe ọ̀rẹ́. Inú wọn yóò dùn láti darí rẹ sí ọ̀nà ti oníwà-bí-Ọlọ́run. Wọn yóò jẹ́ àtìlẹ́yìn fún ọ lórí ìrìn-àjò Krìstẹ́nì rẹ, pẹ̀lú. Ṣàbẹ̀wò sí àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International àti Dove Letter Zone) fún àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí ó lè wúlò fún ọ. Káàbọ̀ Padà sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhìnrere Káàkiri Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023




fi ìwà ìrẹ̀lẹ̀ jẹ́wọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ. Múra láti sọ bí àwọn ẹ̀ṣẹ̀ náà ti rí ní pàtó. Dárúkọ wọn lọ́kọ̀ọ̀kan bí o ṣe ń gbàdúrà. Kò sí ohun tí ó pamọ́ lójú Ọlọ́run (Hébérù 4:13).

*Ọlọ́run Bàbá: Mo jẹ́wọ́ pé mo yapa kúrò lọ́dọ̀ Yín, mo sì padà sí ọ̀nà ìgbésí aiyé mi àtijọ́. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí (**Bẹ̀rẹ̀ sí í sọ àwọn ohun tí o ṣe, láti gbà pé ẹ̀ṣẹ̀ ni wọ́n**). Mo fẹ́ padà sọ́dọ̀ Yín. Mo fi aiyé mi fún Yín lẹ́ẹ̀kan sí i; mo sì ṣèlérí láti dúró lórí ìpinnu mi. Mo dúpẹ́ Bàbá, fún àánú àti ìfẹ́ Yín; àti fún Jésù Krístì tí Ẹ rán láti kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi. Ní Orúkọ Ńlá Jésù ni mo gbàdúrà yìí. Àmín.*

## Kí ló kàn?

Padà sí ṣọ́ọ̀ṣì rẹ, tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì òmíràn tí ó wù ọ́, kí o sì gbèrò láti máa lọ nígbà gbogbo. Yóò jẹ́ ìrànlọ́wọ́ fún ọ tí o bá dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ àdúrà kan. Rántí láti ka Bíbélì rẹ lójoojúmọ́. Sa gbogbo ipá rẹ láti máa gbé ìgbésí aiyé ìwà-mímọ́. Yẹra fún àwọn ènìyàn, àwọn nǹkan, àti gbogbo ibi tí ó lè fà ọ́ padà sínú ẹ̀ṣẹ̀. Kàkà bẹ́ẹ̀, wá àwọn ọmọlẹ́yìn Krístì òtítọ́ láti bá ṣe ọ̀rẹ́. Inú wọn yóò dùn láti darí rẹ sí ọ̀nà ti oníwà-bí-Ọlọ́run. Wọn yóò jẹ́ àtìlẹ́yìn fún ọ lórí ìrìn-àjò Krìstẹ́nì rẹ, pẹ̀lú. Ṣàbẹ̀wò sí àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International àti Dove Letter Zone) fún àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí ó lè wúlò fún ọ. Káàbọ̀ Padà sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhìnrere Káàkiri Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



Àwọn onígbàgbọ́ tí ó wà ní àwùjọ rẹ ti kọ́ ẹ́ sílẹ̀ nítorí ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, bí? Ṣé àwọn èniyàn ń dá ẹ lẹ́jọ́ ní gbogbo ìgbà nítorí àwọn ìwà àìtọ́ tí o hù, ṣùgbọ́n tí o ti kábàámọ̀ rẹ̀? Ṣé wọ́n ti fún ọ ní ààmi *'Ẹlẹ́ṣẹ̀'* ní agbègbè rẹ? Ṣé o ṣì ń gbé pẹ̀lú ìtìjú lẹ́yìn tí o ti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ? O ha rò pé kò tọ́ sí ẹ mọ́, láti ní ìbáṣepọ̀ tí o ní pẹ̀lú Olúwa tẹ́lẹ̀ rí, bí?

Má ṣe banújẹ́, olùfẹ́! Sátánì yóò yára láti sọ fún ọ pé, o kò lẹ́tọ̀ọ́ sí ìfẹ́ àti ìdáríjì Ọlọ́run. Iṣẹ́ rẹ̀ ni, láti rí i pé o juwọ́ sílẹ̀ lórí ara rẹ, kí o wá bẹ̀rẹ̀ sí í rò pé Ọlọ́run kò nífẹ̀ẹ́ rẹ mọ́ - pàápàá nígbà tí o ti kábàámọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ rẹ. Má ṣe gba irọ́ rẹ̀ gbọ́! Ọlọ́run mọ̀ wípé inú rẹ kò dùn nípa ohun tí o ṣe. Síbẹ̀síbẹ̀, Ó ń dúró dè ọ́ láti ṣe ohun tí ó yẹ, gẹ́gẹ́ bí Bíbélì ti sọ ní *1 Jòhánù 1:9*, kí Ó lè gbà ọ́ padà sínú agbo Rẹ̀. Inú Rẹ̀ a máa dùn láti dáríjì wá, nígbà tí a bá yàn láti rìn lọ ní ọ̀nà tiwa, ṣùgbọ́n tí a yí padà sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀. Kò sí ẹnikẹ́ni tí ó fẹ́ràn Ọlọ́run tí a ó yà sọ́tọ̀ kúrò lọ́dọ̀ Rẹ̀, bí kò ṣe nípa yíyàn ti ẹni náà (Jòhánù 10:27-30). Òwe ọmọ onínàákúnàá nínú Lúùkù 15:11-32 ṣe àfihàn ìfẹ́ Rẹ̀ sí wa, àti ìmúratán Rẹ̀ láti dáríjì àwọn tí wọ́n yapa kúrò lọ́dọ̀ Rẹ̀, ṣùgbọ́n tí wọ́n padà; àti bí Ó ṣe dùn mọ́ nínú láti mú wọn padà bọ̀ sí ipò. Ọlọ́run yóò gbà ẹ́ padà bí ẹni pé o kò kúrò lọ́dọ̀ Rẹ̀, bí ó ti wù kí o ti yapa jìnnà tó. Ìfẹ́ Rẹ̀ ni kí a wà pẹ̀lú Rẹ̀ títí láí. Kò fẹ́ kí a ṣègbé rárá (2 Pétérù 3:9). Nígbà tí Jésù Krístì san gbèse àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa lórí igi Àgbélébùú Kálfárì, gbogbo rẹ̀ pátápátá ni Ó san. Yàtọ̀ sí pé Ó san gbèse àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa; Ó máa ń bá wa kẹ́dùn nínú àwọn àìlera wa, pẹ̀lú (Hébérù 4:14-16). Àmọ́, gbogbo wa la ní láti jẹ́wọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa, kí a sì ronúpìwàdà. Ọlọ́run ò ní kọ̀ láti gba èyíkéyìí nínú àwọn ọmọ Rẹ̀ tí ó bá fẹ́ ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Rẹ̀. Ewu tí ó máa wà ni, kí a kọ̀ láti gbà pé a ti ṣẹ̀; kí a sì tún kọ̀ láti ṣe àtúnṣe. Ọlọ́run ni ó ń dá àwọn tí ó wà nínú Krístì láre, kìí ṣe ẹ̀dá ènìyàn (Róòmù 8:33). Súnmọ́ ìtẹ́ oore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀ ní báyìí, láti gba àánú Rẹ̀; kí o sì máa bá ìgbésí aiyé aláyọ̀ rẹ lọ!

## Báwo ni a ṣe lè padà sí ní àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí a bá jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wa, Olóòótọ́ àti Olódodo ni Ọlọ́run láti dáríjì, àti láti wẹ àìṣe-déédé gbogbo nù, kúrò lára wa (1 Jòhánù 1:9).

1. Gbà pé o ti ṣẹ̀.
2. Sọjú abẹ níkòó nípa jíjẹ́wọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, kí o sì múra tán láti yí padà kúrò ninù àwọn ẹ̀ṣẹ̀ náà.
3. Lẹ́yìn náà, gba àdúrà yìí:

* O lè gbàdúrà ní ọ̀rọ̀ tìrẹ; ṣùgbọ́n ríi dájú pé o

Àwọn onígbàgbọ́ tí ó wà ní àwùjọ rẹ ti kọ́ ẹ́ sílẹ̀ nítorí ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, bí? Ṣé àwọn èniyàn ń dá ẹ lẹ́jọ́ ní gbogbo ìgbà nítorí àwọn ìwà àìtọ́ tí o hù, ṣùgbọ́n tí o ti kábàámọ̀ rẹ̀? Ṣé wọ́n ti fún ọ ní ààmi *'Ẹlẹ́ṣẹ̀'* ní agbègbè rẹ? Ṣé o ṣì ń gbé pẹ̀lú ìtìjú lẹ́yìn tí o ti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ? O ha rò pé kò tọ́ sí ẹ mọ́, láti ní ìbáṣepọ̀ tí o ní pẹ̀lú Olúwa tẹ́lẹ̀ rí, bí?

Má ṣe banújẹ́, olùfẹ́! Sátánì yóò yára láti sọ fún ọ pé, o kò lẹ́tọ̀ọ́ sí ìfẹ́ àti ìdáríjì Ọlọ́run. Iṣẹ́ rẹ̀ ni, láti rí i pé o juwọ́ sílẹ̀ lórí ara rẹ, kí o wá bẹ̀rẹ̀ sí í rò pé Ọlọ́run kò nífẹ̀ẹ́ rẹ mọ́ - pàápàá nígbà tí o ti kábàámọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ rẹ. Má ṣe gba irọ́ rẹ̀ gbọ́! Ọlọ́run mọ̀ wípé inú rẹ kò dùn nípa ohun tí o ṣe. Síbẹ̀síbẹ̀, Ó ń dúró dè ọ́ láti ṣe ohun tí ó yẹ, gẹ́gẹ́ bí Bíbélì ti sọ ní *1 Jòhánù 1:9*, kí Ó lè gbà ọ́ padà sínú agbo Rẹ̀. Inú Rẹ̀ a máa dùn láti dáríjì wá, nígbà tí a bá yàn láti rìn lọ ní ọ̀nà tiwa, ṣùgbọ́n tí a yí padà sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀. Kò sí ẹnikẹ́ni tí ó fẹ́ràn Ọlọ́run tí a ó yà sọ́tọ̀ kúrò lọ́dọ̀ Rẹ̀, bí kò ṣe nípa yíyàn ti ẹni náà (Jòhánù 10:27-30). Òwe ọmọ onínàákúnàá nínú Lúùkù 15:11-32 ṣe àfihàn ìfẹ́ Rẹ̀ sí wa, àti ìmúratán Rẹ̀ láti dáríjì àwọn tí wọ́n yapa kúrò lọ́dọ̀ Rẹ̀, ṣùgbọ́n tí wọ́n padà; àti bí Ó ṣe dùn mọ́ nínú láti mú wọn padà bọ̀ sí ipò. Ọlọ́run yóò gbà ẹ́ padà bí ẹni pé o kò kúrò lọ́dọ̀ Rẹ̀, bí ó ti wù kí o ti yapa jìnnà tó. Ìfẹ́ Rẹ̀ ni kí a wà pẹ̀lú Rẹ̀ títí láí. Kò fẹ́ kí a ṣègbé rárá (2 Pétérù 3:9). Nígbà tí Jésù Krístì san gbèse àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa lórí igi Àgbélébùú Kálfárì, gbogbo rẹ̀ pátápátá ni Ó san. Yàtọ̀ sí pé Ó san gbèse àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa; Ó máa ń bá wa kẹ́dùn nínú àwọn àìlera wa, pẹ̀lú (Hébérù 4:14-16). Àmọ́, gbogbo wa la ní láti jẹ́wọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa, kí a sì ronúpìwàdà. Ọlọ́run ò ní kọ̀ láti gba èyíkéyìí nínú àwọn ọmọ Rẹ̀ tí ó bá fẹ́ ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Rẹ̀. Ewu tí ó máa wà ni, kí a kọ̀ láti gbà pé a ti ṣẹ̀; kí a sì tún kọ̀ láti ṣe àtúnṣe. Ọlọ́run ni ó ń dá àwọn tí ó wà nínú Krístì láre, kìí ṣe ẹ̀dá ènìyàn (Róòmù 8:33). Súnmọ́ ìtẹ́ oore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀ ní báyìí, láti gba àánú Rẹ̀; kí o sì máa bá ìgbésí aiyé aláyọ̀ rẹ lọ!

Báwo ni a ṣe lè padà sí ní àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí a bá jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wa, Olóòótọ́ àti Olódodo ni Ọlọ́run láti dáríjì, àti láti wẹ àìṣe-déédé gbogbo nù, kúrò lára wa (1 Jòhánù 1:9).

1. Gbà pé o ti ṣẹ̀.
2. Sọjú abẹ níkòó nípa jíjẹ́wọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, kí o sì múra tán láti yí padà kúrò ninù àwọn ẹ̀ṣẹ̀ náà.
3. Lẹ́yìn náà, gba àdúrà yìí:

* O lè gbàdúrà ní ọ̀rọ̀ tìrẹ; ṣùgbọ́n ríi dájú pé o